# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KỌKÀNLÁ, ỌDÚN 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**OṢÙ KỌKÀNLÁ 2024 – AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ÀWỌN ORIN ÌBẸ̀Ẹ̀RẸ̀**

1. **Ọlọ́run t'Ó mú Ísráẹ́lì la òkun já.**

Tí Ó sì gbà wọ́n kúrò lí oko ẹrú,
Tí Ó rọ̀'jò ónjẹ sílẹ̀ láti ọ̀run,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

**Ègbè**

Ọ̀kan ná lónì, ọ̀kan ná lónì,
B'ákokò tí Ó sin Ísráẹ́lì la òkun;
Ọmọ Rẹ̀ ní un ó jẹ̀, 'torí ọ̀rọ̀ Rẹ́ sọ
Pé, ọ̀kan ná nì Ọlọ́run
Ìyanu lónì.

2. Ọlọ́run t'Ó gba Dáníẹ́lì lọ́wọ́ Kinìún,

T'Ó sì yọ àwọn mẹ́ta n'nú iná'léru,
Ẹni tí àwọn ìràwọ̀ ngbà Tirẹ̀ gbọ́,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

3. Ọlọ́run t'Ó f'ọ̀rọ̀ Rẹ̀ d'áfẹ́fẹ́ dúró,

T'Ó sì nsọ 'bànújẹ́ òní d'ayọ̀ lọ́la,
Ẹni tí Ó yí òkúta 'bojì kúrò,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

4. Ọlọ́run t'Ó wọ itànná ìgbẹ́ l'áṣọ,
Ẹni t'Ó mú omi ṣàn n'íyàngbẹ́ ilẹ̀,
Tí Ó wẹ ẹlẹ́ṣẹ̀ mọ́ nínú èrí rẹ,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

1. **Ha ẹgbẹ́ mi, ẹ w'ásià!**
Bo tí nfẹ́ lẹlẹ̀!
Ogun Jésù fẹrẹ̀ dé ná,
A fẹ́rẹ̀ ṣẹ́gun.".

"D'odi mú, Èmi fẹ́rẹ̀ dé"
Bẹ́nì Jésù wí,
Rán 'dáhùn padá s'ọ́run pé
"Àwa ó dì mú".

2. Wo ọ̀pọ̀ ogun tí mbọ̀ wá;
Èṣù nkó wọn bọ̀;
Àwọn alágbára nṣubú
A fẹ́ dàmú tán!

3. Wo àsíá Jésù tí nfẹ́
Gbọ́ ohùn ìpè;
A ó ṣẹ́gun gbogbo ọ̀tá
Ní orúkọ Rẹ.

4. Ogun ngbóná gìrìgìrì
Ìrànwọ́ wa mbọ̀;
Balógun wa mbọ̀ wà tete,
Ẹgbẹ́, tújúká!

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Bàbá mi, jẹ́ kí a kó àwọn alùmọ́nì ọ̀run jọ láti ràn mí lọ́wọ́, kí n lè gba gbogbo ibùkún mi lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Bàbá mi, jẹ́ kí ìmọ́lẹ̀ Rẹ lé òkùnkùn nínú ayé mi kúrò lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá mi, bẹ̀ mí wò lónìí pẹ̀lú ọwọ́ ògo Rẹ, kí O sì jẹ́ kí gbogbo òkùnkùn nínú ayé, ilé àti iṣẹ́ mi pòórá, ní orúkọ Jésù.
4. Agbárakágbára t'ó ti jẹ́ẹ̀jẹ́ wí pé nkò ní bọ́ kúrò nínú wàhálà, ìwọ kọ́ ni ẹlẹ́dà mí, kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo agbára òkùnkùn tó nlo ọgànjọ́ òru láti pọ́n ayànmọ́ mi lójú, àrá Ọlọ́run yóò pa ọ́ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ẹrù ibi tí wọ́n gbé sórí ayé mi láti inú ìyá mi wá, tó mba ohunrere jẹ́ nínú ayànmọ́ mi, iná Ọlọ́run yóò dáná sun ọ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ẹrù ibi ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn láti dá ìrìn-àjò mi sí Ilẹ̀ Ìlérí dúró, gbiná báyìí, ní orúkọ Jésù.

# ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Éksódù 15:2:** OLÚWA li agbára àti orin mi, Òn li Ó sì di ìgbàlà mi: èyí li Ọlọ́run mi, èmi ó sì fi ìyìn fun U; Ọlọ́run bàbá mi, èmi ó gbè E lékè.

**Deuterónómì 20:4:** Nitorípé OLÚWA Ọlọ́run nyín ní mbá nyín lọ, láti bá àwọn ọ̀tá nyín jà fún nyín, láti gbà nyín là.

**Deuterónómì 31:6:** Ẹ ṣe gírí, kí ẹ sì mú àyà le, ẹ máṣe bẹ̀rù, ẹ má sì ṣe fòyà wọn: nítorípé OLÚWA Ọlọ́run rẹ, Òn li Ó mbá ọ lọ; Òn kì yóò fi ọ́ sílẹ̀, bẹ́nì kì yóò kọ̀ ọ́.

**Orin Dáfídì 31:24:** Ẹ tújúká, yóò sì mú yín lí àyà le, gbogbo ẹ̀yin tí ó ní irètí níti Olúwa.

**Ìsàíàh 40:31:** Ṣùgbọ́n àwọn tí ó bá dúró de Olúwa yóò tún agbára wọn ṣe; nwọn o fi ìyẹ́ gun òkè bí idi; nwọn ó sáré, kì yóò sì rẹ̀ wọ́n; nwọn ó rìn, àrẹ́ kì yóò sì mú wọn.

**Ìsáíàh 41:10:** Ìwọ má bẹ̀rù; nítorí m'O wà pẹ̀lú rẹ, má fòyà; nítorí Èmi ni Ọlọ́run rẹ: Èmi Ó fùn ọ ní okun; nítòtọ́, Èmi Ó ràn ọ́ lọ́wọ́; nítòtọ́, Èmi Ó fi ọwọ́ ọ̀tún òdodo mi gbé ọ sókè.

**1 Kọ́ríntì 10:13:** Kò sí ìdanwò kan tí ó ti íbá yín, bíkòṣe irú èyítí ó mọ níwọ̀n fún ènìyàn: ṣùgbọ́n olódodo ni Ọlọ́run, ẹnití kì yóò jẹ́ kí a dán yín wò ju bí ẹ̀yin ti lè gbà; ṣùgbọ́n tí yóò sì ṣe ọ̀nà àtiyọ pẹ̀lú nínú ìdanwò nà, kí ẹ̀yin kí ó ba lè gbà á.

## <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo iná àjèjì ọ̀tá tí wọ́n yàn láti jó èmi àti àwọn ọmọ mi, pa ọ̀tá run nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára tó n fi èrè iṣẹ́ mi pọ́n mi lójú, túmisílẹ̀ nípa iná, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
5. Àìlera tí ọ̀tá nlò láti fi bámi jà, fi ayé mi sílẹ̀, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Níbo ni Olúwa Ọlọ́run Èlíjàh wà? Dìde, jẹ́ kí ògo mi dìde, kó sì tàn, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo éékún ibi tó n tẹ̀ba lòdì sí ìfẹ́ àti ìpinnu Ọlọ́run fún ayé mi, kú báyìí, ní orúkọ Jésù.